# Irohin Yoruba

NO. 830. May 3 — May 9, 1961 KOBO MEJI (2D)


**Lakaye Ọrọ**

NIGBANA ni mo wo gbogbo isẹ Ọlọrun, pe enia ko le ridi isẹ ti a nse labẹ ọrun nitoripe bi enia tilẹ gbiyanju ati wadi rẹ, sibẹsibẹ ki yio le ri i, ati pẹlupẹlu bi ọlọgbọn enia rẹ lati wadi rẹ, sibẹ ki yio le ridi rẹ.




Jẹ egbogi ti o daraju fun ọmọde

O wa fun tita kakiri ile-egbogi


# ADAJỌ JU ADAJỌ SẸWỌN

**OLOYE Emmanuel A. Şosanya, ti o ti nse Adajọ Kotu Ibilẹ ni Ikẹnnẹ ri, gba idajọ ẹwọn ọdun marun ni Kotu Kekere l'Eko ni ọjọ Ẹti ti i se ọjọ kejidinlọgbọn oşu ti o kọja yi.**

Adajọ Agba Kotu Kekere na da a lẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa fi sun pe o ta ilẹ Ologbe St. Matthew Daniel, ko si fi owo ilẹ na jişẹ fun awọn ti o ni ogun ologbe na. Iye owo ilẹ na jẹ ẹdẹgbeje ponun-le-ẹdogbọn ati şile mẹfa (£1,325 6s.).

Siwaju idajọ titun yi, Adajọ Kotu Kekere kan l'Eko ti sọ ọdaran yi sẹwọn ọdun mẹfa fun pe o jẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa fi sun nigbana pe o ta ilẹ onilẹ lọna ẹru.

Isẹ gbanjọ tita ni ọdaran oloye na ti nşe ri l'Eko

## Iyawo Tarka fi isẹ silẹ lati şe "Kampeni"

IROHIN ti kan lati Jos wa pe Iyaafin Francisca Tarka, iyawo Ọlọla J. S. Tarka, olori Ẹgbẹ UMBC dapọ mọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni agbedemeji aalą Ipinlẹ Ariwa (Mid-Belt)) ti fi isẹ rẹ silẹ nitori a ti şe "Kampeni" (ikede fun ibo) fun ẹgbẹ ọkọ rẹ.

Iyaafin Tarka jẹ olukọni ni ile ẹkọ kan ni Gboko, ni ilu Markudi, owo rẹ lọdun si jẹ adọtalerinwo ponun. O fi isẹ na silẹ o si ti şe "Kampeni" pupọ fun idibo si Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Ariwa eyiti nwọn yio şe ni ọla, ọjọ Ọjọbọ ti i şe ọjọ kẹrin oşu yi.

## Aja le ọmọ ile iwe kan pa

GUSAU.

LENULỌLỌYI ni ọmọ ile-iwe Ijọba Ibilẹ Gusau (N.A. Junior Primary School) kan ti oruko rẹ nję Oseni Gusau, ọmọ ọdun mejila fojana lojiji nigbati aja digbolugi kan nle e.

O ko s'ẹnu mọto akẹru, o si pa a ni apafọn. Awọn ọmọ ile iwe ẹlẹgbẹ rẹ si fi ibanujẹ ba wọn gbe e lọ si itẹ oku nibiti nwọn sin si.

## Edẹgbẹta Enia tan si Haji

KANO.

LEHINTI irohin ti kan nipa awọn enia mejidinladọrin ti nwọn ti tan si Haji, ti nwọn si ti wa won wa si Kano, ni iro miran tun de lati Jẹddah pe nwọn tun wa ẹdẹgbẹta (500) ero Haji miran wa silẹ. Wo oju ewe kẹta.

# Ara Ipinlẹ Ariwa yio dibo lọla

## Ẹgbẹ Afẹnifẹre şe ileri idẹra mẹrinla fun awọn ara Ipinlẹ na

AWỌn ara Ipinlẹ Ariwa yio dibo ni ọla, ọjọ Ọjọbọ ti i şe ọjọ kẹrin oşu yi. Ni ọjọ Ọjọbọ ti işẹ ọjọ kẹrinlọgbọn oşu ti o kọja yi ni Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) kọ iwe eto awọn ileri idẹra pataki mẹrinla kan ti awọn yio şe fun awọn enia Ipinlẹ Ariwa, ti nwọn ba le dibo fun awọn asoju ti awọn ba yan lati dibo fun wọle Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Ariwa na ni ọla.



OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ, OLORI ẸGBẸ AFẸNI FẸRE

Ninu awọn eto ileri idẹra na, Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni awọn yio san şile mẹfa o din kọbọ meji (5s. 10d.) ojumọ fun awọn oşişẹ lebira. Nwọn yio şe eto Ijọba rere si inu awọn Kotu Ibilẹ ati ti Alkali, nwọn yio si da Ile-iwe ofẹ silẹ fun awọn ọmọde alakọbẹrẹ yika gbogbo ilẹ wọn.

### ETO ẸKỌ

Nwọn ni awọn bu ọwọ fun eto ẹkọ işẹdalẹ wọn, şugbọn ko yẹ ki awọn eto ẹkọ na jẹ idiwọ fun anfani ilọsiwaju. Nitori idi eyi, Ẹgbẹ Afẹnifẹre yio şe akiti yan lati sọ Ijọba Ibilẹ di Ijọba rere ti o ni agbara lati şe ifẹ awọn ara ilu.

Ninu iwe eto ileri na, Ẹgbẹ Afẹnifẹre so pe:

"Nisisiyi ko si apẹẹrẹ Ijọba rere nibiti agbara wa lọwọ awọn enia ilu ninu Ijọba Ẹgbẹ Olomi (NPC) awọn Ẹgbẹ Alatako Igbimọ ti o ba sọrọ fun anfani awọn mẹkunnu enia Ipinlẹ Ariwa yio jiya pupọ. Nwọn ko gba wọn laye lati pade ba ara wọn sọrọ, lati polowo idibo, nwọn ko si gba wọn laye ẹtọ wọn pe ki nwọn dibo fun wọn ni gbẹfẹ ati irọrun."

"Ẹgbẹ Afẹnifẹre yio fi opin si ofin ihamọ ati ipaala-ilẹ fun anfani ẹtọ ẹnikẹni."

### IŞẸ AGBẸ

"Ko si ilu ti ilẹ rẹ ba lilo ẹrọ-iroko mu ju gbangba inu papa ilẹ Ipinlẹ Ariwa Naijiria lọ, sibẹsibẹ na, ko si ibiti ọmọ-enia gbe nlo ara ni alodanu nitori ire diẹ kinun ti o dabi ti Ipinlẹ Ariwa".

"Yio jẹ igbiyanju pataki fun Ijọba Ẹgbẹ Afẹnifẹre Ipinlẹ Ariwa lati mu eto fifi ẹrọ şe işẹ agbẹ wa si gbogbo Ipinlẹ Ariwa nipa dida ilẹ awọn agbẹ kọọkọọkẹ ti o wa nibẹ nisisiyi pọ

Wo oju ewe kẹwa

# EKO AKETE

## (Lati owo Qmo-Onile)



## Awolowo Gba'yi

## Oye Balogun

## Ero Haji

E ma a ka lae
IROHIN YORUBA
nigbagbogbo fun irohin aladun




# Awọn ọmọ Odo ṣe ọdun Akoogun



# Irohin igbeyawo, ikomọjade, ifinijoye





# REṘIN

## Ki ara rẹ o tuka

Lati ọwọ "M.O.A."

## Ẹgbẹ onișowo Idanre șe ajọdnn

IDANRE



# K'ALARA SUNRAKI

## Lati ọwọ "OMI ATA"

# MO JUBA!

IBA, k'iba ṣẹ, mo juba!
Mo juba Oluwa ilẹ ati omi,
Ọba Edumare to joko lori itẹ lọrun,
T'o nfoju anu wo iṣesi ọmọ enia.

* * *

MO juba awọn Ọba alade ile aiye,
Awọn aṣoju agbara at'ẹmi orilẹ-ede;
Mo juba awọn ajọba madade, ijoye ilu dede,
Awọn alarina larin ọlọla at'otoṣi.

* * *

MO juba awọn to ntọka wa sọna ọrun rere,
Awọn ojiṣẹ ihinrere, akede igbala;
Mo juba awọn Tiṣa-olukọ ewe,
Awọn to nkọ oṣelu to nṣofin "Ṣukuru",

* * *

MO juba awọn agba t'o mọ ipinlẹ aiye ati ọrun,
Awọn ti iriri sọ d'anjọnu ninu enia:
Mo juba awọn ọlọgbọn at'amoye,
Awọn alagbara bi Ọlọrun ba ṣatilẹhin.

* * *

MO juba awọn oṣelu, awọn aṣofin,
Awọn onidajọ ati awọn amofin;
Awọn oniṣegun ati awọn adahunṣe
Awọn "Sisi" Nọsi at'awọn iya-abiye.

* * *

MO juba awọn oniwe irohin ati at'awọn onkawe wọn,
Awọn onisẹ-ọwọ at'awọn onisowo:
Awọn akọwe at'oṣisẹ Ijoba dede.
Awọn agbẹ t'o yẹ k'a pe ni "babasalẹ".

MO juba Ọsọ Ṣobọ Arobiodu,
Ọmọ Ṣowande Ọfanran, alaṣaro ọrọ;
Mo juba Atioro ọmọ Atiala, Ọba ninu ẹiye,
Eni onjẹ ojọ gbalohun lọ, ti ko dẹ ṣarofọ.

* * *

MO juba o, mo juba agba o,
Iba ọmọde, iba agba;
Mo ki ara ile, mo ki ara oko,
Gbogbo wa ku ayọ Ominira.

* * *

AKU ajaye;
Iba ọmọde iba agba.
Gbogbo nyin k'ẹ wa tẹtileri, k'ẹ ma a gbọ.
Mo ni ọrọ nla lati sọ, bẹni ọrẹ mi.
Fun ọlọgbọn ati were oṣelu asiko.

* * *

ENYIN yi nka iwe-irohin lati mu arufin,
Ẹ jọwọ gba ogbufọ t'o gbọ ede mi re,
"Tori agbọigbọtan Egun ni da ija silẹ;
Ẹnyin abaniwa-ọran ṣe ẹ ngb'ohun mi?
Omi Ata de, k'alara sunraki.

* * *

NDAO, ọrẹ, jọwọ maṣe foiya si t'emi,
Emi ko ni sọ eyi ti ko tọ,
Ṣugbọn emi ko ni ṣaisọ ohun ti ko sunwọn;
Nitori a gbọdọ sọ f'awọn oṣelu ki nwọn ṣọtọ.
A gbọdọ sọ fun awọn adajọ ki nwọn maṣe pada lẹhin ododo,
Ki ominira Naijiria ba gbilẹ ninu ifẹ at'irẹpọ.
Bẹni; emi yio wi, emi yio sọ.
K'alara sunraki.

* * *

KINI iwọ wi? Ẹwọn tabi kinla?
Ori pipa ki i pa gunugun,
Gẹgẹ-ọrun ki i pa akalamagbo;
Arofọ ko ni gbemidẹ bi ẹran,
Emi ko ni kọrin de ọgba ẹwọn:
A ko ni tori gbigbo paja
A ko ni tori kikan p'agbo;
Omi ata ko ṣe bọju,
A ko ni tori OTITỌ gbemi de.
Oju ko f'ẹra ku o!.

# Alọ o? Alọ!

EKINI—Ẹran nla anila malopo.
EKEJI—Papa njo janganna nwo ran.
ẸKẸTA—Nwọn ni ki ngbe e wa mo gbe e wa, nwọn wa ni ki ngbe e lọ nko le gbe e lọ mọ.
ẸKẸRIN—Igi baba wa lailai, igi baba wa laelae ewe kan ni i ni, egbo kan ni i ni.

## ITUMỌ ALỌ

Ekini—Ẹja inu omi.
Ekeji—Ogiri ile.
Ẹkẹta—Ogiri ile.
Ẹkẹrin—Ẹẹkan.

# Ẹnikan ki i ṣ'odi

(Lati oju ewe kẹrin)
kan ilu Ile-Ifẹ nigbana wipe:—
Ibi ẹ ba ti mu "Fani" wa o, ẹ yara mu re bẹ.



ERUKOBODO

Gbolohun orin yi ni ko tun jẹki o le ma a lọ rafanda larin Ile-Ifẹ mọ titi di oni oloni yi.

L'ọna kẹta, iwa abuku ti a nsọ wipe Ọgbẹni Kayọde hu si Ọni ati Gomina yi, eyi ki iṣe akọkọ, iru iwa abuku kan bẹ ẹ ti ṣẹlẹ lati sakani rẹ si Ologbe Ọba Alaiyeluwa Adelẹkan (Olubuṣe) Ọni Ile-Ifẹ, ni igba aiye rẹ, ṣugbọn, awọn ti ọrọ na ṣ'oju rẹ lasiko igbana ri i daju gbangba wipe, loto, ẹnikan ki iṣ'odi, tabi huwa abuku si Ọni, ki araiye tun sọrọ ẹni na si rere, ayafi ti oluwarẹ ba tọrọ aforijin.

**ỌLỌLA AKERELE**

Ohun pataki ti mo fẹ sọ fun awọn Ọmọ-O'dua ni igboro ilu Ifẹ-Ilia ati agbegbe rẹ ni wipe, ẹ ki iṣẹ ẹni abuku lati owurọ ọjọ, asiwaju ni a ti ṣe nyin, Olodumare ko ni jẹki ẹ pada di ero ẹhin.

Ọrọ ọmọluwabi pẹlu ti janduku enia ko le papọ, ẹ yago fun ẹgbẹ alabuku, abuku ti nwọn ti diran mọ wọn l'ara, nwọn ko mọ ọba l'ọba, bẹni, nwọn ko mọ ijoye ni ijoye, ani, nwọn ko tilẹ mọ agba l'ẹgbọn.

Ẹ jinna si ẹgbẹ oniyọrọ, ẹ tari ago Adiẹ wọn siwaju ki ẹ raye gbaruku ti Ọlọla Akerele lẹhin nipa piparapọ nyin di ọpọ aṣla Ẹgbẹ Afenifẹre mu giri-giri.

Ọlotu, mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi, Oluwa ko ni fi abuku kun ọrọ nyin.



O NJẸKI NGNI AGBARA ATI ILERA
NI NAIJIRIA NI A TI ṢE AMAMA
AWỌN ALAGBATA RẸ NI: GLAXO—ALLENBURYS (NIGERIA) LTD,
P. M. B. 2310, LAGOS, ati pẹlu ni ABA ati KANO.

